# AYÉ WÀ FUNRA RẸ̀ NI TABI A DÁ A?

## Gẹnẹsisi 1:1-31; II Peteru 3:1-14

### ẸKỌ 92 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Nitori ninu rẹ̀ li a ti dá ohun gbogbo, ohun ti mbẹ li ọrun, ati ohun ti mbẹ li aiye, eyiti a ri, ati eyiti a kò ri, nwọn iba ṣe itẹ́, tabi oye, tabi ijọba, tabi ọla: nipasẹ rẹ̀ li a ti dá ohun gbogbo, ati fun u" (Kolosse 1:16).**

**I Aṣẹ ti o Ga Ju Lọ -- Ọrọ Ọlọrun**

1. Ọlọrun ti mọ̀ tẹlẹ bi ọkàn ọmọ eniyan yoo ti buru tó, O si ti mu ki Ọrọ Rẹ̀ yanju kedere, Johannu 1:3; Marku 10:6; Romu 1:20; Kolosse 1:16
2. Ọpọlọpọ ni o ti kọ̀ Ọrọ Ọlọrun, Orin Dafidi 53:1; Romu 1:21-25
3. Ogunlọgọ eniyan ni o n gbiyanju lati sin oluwa meji -- ẹkọ ọgbọ́n ori nipa iṣẹdalẹ ayé ati Bibeli, Matteu 6:24; II Peteru 2:12

**II Awọn Ẹlẹgan ni Igba Ikẹyin**

1. A kò gbọdọ sẹ́ agbara Ọlọrun ti O fi dá ayé ki a si sọ pe "ayé ṣà dédé wà funra rẹ̀ ni", I Kọrinti 15:38-42; Genesisi 1:1-31
2. A kò le sẹ́ otitọ yii pe eniyan ti ṣubu, Genesisi 3:1-24
3. A tú aṣiiri awọn ẹkọ ti kò fi idi mulẹ, a si kọ̀ wọn, II Peteru 3:1-14

**III Ohun ti Igba Yoo Fi Hàn**

1. Ọlọrun gan ọgbọ́n eniyan, I Kọrinti 1:19-21; 2:6-8; 3:19, 20; Jakọbu 3:15
2. Bibeli ni ó gbọdọ jẹ́ atọ́nà ati alaṣẹ fun wa, Oniwasu 12:14; Ifihan 22:18, 19

## ALAYE

**Bibeli ni Alaṣẹ**

Fun ọmọ Ọlọrun ti o ti mọ agbara Ẹmi ti n yí eniyan pada, ti o si ti jẹ adun awọn ileri ti a ṣe fun un ninu Ọrọ Ọlọrun, gbolohun kan lati inu Iwe Mimọ́ bi eyi, pe, "Li atetekọṣe Ọlọrun dá ọrun on aiye," jẹ ọrọ ti yoo tẹ́ ẹ lọrun nipa iṣẹda eniyan ati ipilẹṣẹ ayé. Ṣugbọn o gbà pe ki a fi iṣiwere ti o wà ninu igbekalẹ awọn eniyan hàn awọn alaigbagbọ, awọn ẹlẹgan ati awọn alaibikita. Dajudaju àya awọn ẹlẹgan yoo maa mura papa lati huwa ibi, lati gba èké gbọ́, ki wọn si wà ni ipo ọta si Ọlọrun: "Nitori ero ti ara ọtá ni si Ọlọrun: nitori ki itẹriba fun ofin Ọlọrun, on ko tilẹ le ṣe e" (Romu 8:7).

**Ṣiṣe Aigbagbọ́ Pé Ọlọrun Wà**

Kò si àye fun Ọlọrun ninu ẹkọ ọgbọ́n ori nipa iṣẹdalẹ ayé. Bayii ni ọ̀kan ninu awọn ti o kọkọ tẹwọgba ẹkọ yii wi: "Bi iwọ ba gba Ọlọrun layè rara, kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ iwọ kò ni ṣai gba A láyè patapata." Bi ẹni kan ninu awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé ba jẹwọ pe "Ẹni kan ti a le pe ni Ọlọrun" wà, kó ju ọlọrun ero ori nipa iṣẹdalẹ aye: Ọlọrun, ẹda, tabi apapọ ọrun ati agbaye – nnkan kan naa ni gbogbo wọn." Awọn kan tilẹ wi pe eniyan funra rẹ̀ ni Ọlọrun. Ninu Ọrọ Rẹ̀, Ọlọrun sọ fun ni pe awọn eniyan yoo sẹ́ Oun: "Aṣiwere wi li ọkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun kò si."

Ọkan ninu awọn atakò ti awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé ni si Ọlọrun ati Bibeli Rẹ̀ ni pe, ko si iyipada, bẹẹ ni kò si ilọsiwaju ninu ero pe Ọlọrun wà ati ninu akọsilẹ inu Bibeli eyi ti a ṣe nigba ti awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye wi pe, "ko si òye nipa imọ ijinlẹ." Rara; kò si ayipada nitori lati atetekọṣe ni Ọlọrun ati Ọrọ Rẹ̀ ti wà ni pipé. Kò si eredi ti wọn le fi yipada.

**"Iran Ọ̀bọ"**

Ni ọ̀pọlọpọ ile-iwe ni a n kọ́ awọn ọmọde pe ibatan ọbọ ni wọn jẹ́; pe nibi gbogbo ni apẹẹrẹ idagba soke ẹda wà; pe Bibeli kò ṣe deedee pẹlu ẹkọ imọ-ijinlẹ ti ayé ọlaju ti a wà yii. Ẹkọ yii daamu ọkàn ogunlọgọ eniyan o si tàn wọn jẹ; wọn n kẹgan Bibeli, Satani si ti ti ipa bẹẹ ri ọna ti o yá ju lọ lati fi fa awọn eniyan kuro lọdọ Ọlọrun: "Nwọn ó si yi etí wọn pada kuro ninu otitọ, nwọn ó si yipada si ìtan asan."

**Ohun Ti O Mú Ariyan-Jiyan Wá**

Ohun ti o n dun awọn ti kò gbagbọ pe Ọlọrun wà ati awọn ẹlẹgan ki i ṣe bi o ti pé to ti ayé ti wà bi ko ṣe "ibi ti eniyan ti jade wá," nitori eyi ni yoo yanju ibeere nipa boya Ọlọrun Ẹlẹda kan wà ti o dá ohun gbogbo. Ohun ti o maa n ṣẹlẹ ni pe gbogbo awọn ti o tẹwọ gba ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ẹda ni ojulowo ni wọn sọ pe Ọlọrun kò si. Wọn wi pe awọn gbọdọ pa ero pe a dá eniyan "rẹlẹ diẹ ju awọn angẹli lọ" tì, ki wọn si kẹkọọ nipa rẹ̀ gẹgẹ bi eniyan ti i maa yẹ "kokoro titun" wò. Kò rọrun lati sọ boya nitori wọn jẹ́ ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé ni wọn ṣe wi pe Ọlọrun kò sí, tabi nitori wọn wi pe Ọlọrun kò sí ni wọn ṣe jẹ ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé.

**Wọ́n Mura lati Gba Eke Gbọ́**

Ni nnkan bi ọgọrun ọdun sẹyin, "iyemeji gbode kan bi ikún omi." Awọn eniyan fi imọ ijinlẹ (science) dipo Ọlọrun. Ọkunrin kan tilẹ sọ pe ẹru ba oun lati ní igbagbọ ninu Ọlọrun nitori ọ̀wọ̀ ti oun fun imọ ijinlẹ. Ni akoko naa awọn ti o ti kẹyin si Ọlọrun ti wà ni imurasilẹ lati gba arofọ ọgbẹni Darwin ti akọle rẹ i ṣe, "Lori ipilẹṣẹ Orişirişi Nnkan Ẹlẹmi Nipa Yiyàn Gẹgẹ Bi Iṣe Ẹda" ti o kọ jade ni ọdun 1859. Ọlọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé kan paapaa tilẹ jẹwọ pe "Lai pẹ rara lẹyin ti wọn gbé arofọ pe ayé kàn dede wà jade ni iwa pipa ara-ẹni funra ẹni gbode kan bi igbi omi okun jake- jado England ati gbogbo agbegbe Iwọ̀-oorun orilẹ-ede awọn Alawọ funfun." Bakan naa, pipa ara-ẹni funra ẹni nipa ti ẹmi ni o saba maa n tẹle arofọ ẹkọ pe awọn nkan ẹlẹmi kan dede wa.

## Kò si Iṣubu

Gẹgẹ bi awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé ti n wí, kò si eredi lati ni Olugbala kankan nitori eniyan kò fi igba kan ṣubu ri. Wọn wi pe nigba gbogbo ni eniyan ti n tẹ siwaju ju ti atẹyinwa lọ. Wọ́n gba eke gbọ́:

**"Ati pẹlu itanjẹ aiṣododo gbogbo fun awọn ti nṣegbé;**
**nitoriti nwọn kò gbà ifẹ otitọ ti a ba fi gbà wọn là.**
**"Ati nitori eyi, Ọlọrun rán ohun ti nṣişẹ iṣina si wọn, ki nwọn ki o le gbà eke gbọ́" (II Tẹssalonika 2:10, 11).**

**Alaye Lori Ẹkọ Ọgbọn Ori Nipa Iṣẹdalẹ Ayé**

Ẹni kan ti o fara mọ ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye ti ṣe alaye pe o jẹ́ ohun ti o n ṣẹlẹ si eweko ati ẹranko ni gbogbo ayé nigba gbogbo ati lai si idaduro.

Gbogbo ohun ti o n ṣẹlẹ si ohun ẹlẹmi bi o ti n dagba ni alaye wà fun ninu ẹkọ yii. Ọpọ eniyan ni a maa n tan jẹ nipa ọrọ yii "idagbasoke." Wọn rò pe itumọ rẹ̀ ko ju bi nnkan ti o dagba lasan lọ, gẹgẹ bi igi iroko ti o ti di igi nla ṣe bẹrẹ lati igi kekere, ti ọ̀pọ̀lọ ti inu dègbènseri tabi legbénlègbé wá, ti labalaba ti inu ekùkù rẹ̀ wá, ati bi ọlẹ̀ ninu obinrin ṣe n dagba di ọmọ. Otitọ ni iru idagbasoke bayii wà, ṣugbọn ki i ṣe iru eyi ni awọn ọmọlẹyin Darwin n pe ni idagbasoke.

"Idagbasoke" gẹgẹ bi a ti n lo ọrọ yii jake-jado ni ode oni, n sọ nipa ohun kan ti o ti dá wà funra rẹ̀ patapata lai si ọwọ iyanu Ọlọrun ninu iṣẹda ohun naa, nipa eyi ti gbogbo ohun ẹlẹmi ti o wà laye lonii ti ti inu ohun kan ṣoṣo naa jade wá, ti ohun kan ṣoṣo naa si ti wà ni ọdun gbọọrọ sẹyin ninu omi okun kan lọna jijin rẹ̀. Nipa ohun ti o dá wà funra rẹ̀ naa, gbogbo ẹyẹ, ẹja, ọ̀ni, ẹranko, ọbọ, ati eniyan ni iran wọn jade wá lati inu ohun ẹlẹmi kekere kan ṣoṣo yii ti o kàn dede bá ara rẹ̀ ninu ayé ni aimoye ọdun sẹyin.

## Iran ti o Dede Wà

Nigba ti a ba beere pe bawo ni "ohun ẹlẹmi kinnkinni" akọkọ naa ti ṣe wáye, o di dandan fun ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé lati jẹwọ pe oun kò mọ̀ ọn. Ṣugbọn oun ko ni fẹ sọ pe Ọlọrun ni O dá a. Eyi ni yoo jẹ idahun rẹ̀ pe, o dede ṣẹlẹ bẹẹ ni, pe ẹmi ti inu ohun ti kò ni ẹmi jade wá. O tun gbiyanju lati ṣe alaye pe orişi afẹfẹ mẹrin ni o dede dapọ mọ ara wọn (carbon, hydrogen, nitrogen ati oxygen) ti o si gbina, abayọri rẹ̀ si ni eyi ti o mu ohun ẹlẹmi kinnkinni naa wáye eyi ti o si wá dagba soke di eniyan lẹyin ẹgbẹẹgbẹrun lọna ẹgbẹẹgbẹrun ọdun. Ṣugbọn sibẹ ọgbẹni yii kò sọ ibi ti awọn afẹfẹ wọnyii ti jade wa.

Ogunlọgọ awọn eniyan ninu awọn onimọ̀-ijinlẹ ni wọn ti pa erokero yii ti pe ohun ẹlẹmi kàn dédé bẹrẹ funra rẹ̀ ni, nitori wọn ti dá ọgbọn leralera lati dá ẹmi, kò si si ẹni ti o ti i daṣa lati kede pe oun ti ṣe aṣeyọri. Nipasẹ ohun ẹlẹmi nikan ṣoṣo ni ohun ti o ni ẹmi ti le wáye. A kà ninu Bibeli ibi ti ẹmi ti jade wá: "OLUWA Ọlọrun si fi erupẹ ilẹ mọ enia; o si mí ẹmí ìye si ihò imu rẹ̀; enia si di alãye ọkàn" (Gẹnẹsisi 2:7).

## Awọn Agbọjẹgẹ

Awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin, agba ọkunrin ati agba obinrin, ati awọn oniwaasu wà ti wọn fẹ lati fara hàn bi ẹni igbalode ninu ẹkọ "imọ ijinlẹ," ṣugbọn ti ko fẹ ki a pè wọ́n ni ọmọ iran ọbọ. Wọn wi pe awọn gbagbọ pe Ọlọrun ni O dá apapọ ọrun ati ayé, ṣugbọn wọn fẹ ṣe adalu igbagbọ yii pọ̀ mọ "imọ ijinlẹ" ati ohun ti awọn

aráyé fara mọ́. Wọn kọ apa kan ẹkọ awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé nibi ti wọn ti wi pe lati inu ẹranko ni eniyan ti dagba soke, ṣugbọn arofọ awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye ti dà wọn loju rú nipa awọn apata ti wọn wi pe o ti wà lati ọkẹ aimoye ọdun sẹyin, ninu eyi ti wọn sọ pe wọn ti ri "egungun awọn ọbọ-deniyan ati awọn ẹranko ti iru wọn kò si mọ́" eyi ti wọn ro pe "o fi idi ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé mulẹ."

Ẹni kan ti wi pe eniyan le gba ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye gbọ ki o si tun jẹ Onigbagbọ bakan naa bi ko ba da àyà de eyikeyi ninu mejeeji pupọpupọ. Ko ṣe e ṣe lati gbagbọ pe n ṣe ni ohun gbogbo kan dédé wà, pe ko si Ọlọrun Ẹlẹda kankan, pe lati ayebaye ni iwa ọmọ eniyan ti n dara si i – lai si àyè fun iṣubu eniyan ati bi o ti di ọranyan fun un lati ni Olugbala kan – ki o si tun gbagbọ pe "li atetekọṣe Ọlọrun dá ọrun on aiye," gẹgẹ bi Bibeli ti wi pe O ṣe.

**Ọrọ-Odi**

Ẹkọ ọgbọ́n ori nipa iṣẹdalẹ ayé tilẹ sọ pe lati inu agbaye ni Jesu ti ṣẹ́yọ wá, pe Oun paapaa dagba soke lati inu iran ẹranko ni. Ninu ẹkọ nipa ayé eyi ti wọn kọ́ awọn ọmọ kekere, ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹda ayé kan ṣalaye ọna ti o rò pe Jesu gbà fi wá si ayé: "Ṣaaju, ohun kinnkinni ẹlẹmi kan fara han lori adagun omi kan ti o lọ́ wọọrọ, lẹyin naa, ohun kinnkinni naa bẹrẹ si di pupọ,bẹẹbẹẹ o di gèdègẹdẹ elewe wẹwẹ. bẹẹbẹẹ awọn ẹja keekeekee onipẹ bẹrẹ si luwẹ ninu omi naa,.bẹẹbẹẹ wọn di ọ̀ọ̀kùn ti n rákò, kokoro, ẹja, ọ̀pọlọ́, alangba, awọn ẹranko laelae, ejo ti n fò, àgbọnrin, ọbọ, eniyan. bẹẹbẹẹ Abrahamu bẹrẹ si rin kiri, awọn ọmọ Israẹli jade ni Egipti, awọn Ju fi idi ẹsin wọn mulẹ, nikẹyin a ri ọdọmọbinrin ti o pé ju lọ ni, ani Maria ti Nasarẹti. Wakati naa de fun owurọ ọjọ titun, imọlẹ ọjọ titun naa si ni ibi Jesu." Dajudaju lai si ewédò naa ki ba ti si Maria; lai si ọbọ ki ba ti si Abrahamu, lai si ọ̀ọ̀kùn, ayé ki ba ti mọ Kristi. Eyi jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ọrọ-odi ti ikẹyin ọjọ: "Nwọn si pa ogo Ọlọrun ti ki idibajẹ dà si aworan ere enia ti idibajẹ ati ti ẹiyẹ, ati ẹranko ẹlẹsẹ mẹrin, ati ohun ti nrakò" (Romu 1:23).

**Awọn Ayẹwo Ẹjẹ**

"Ẹjẹ ṣe pataki" ni ọrọ ẹni kan ti o gbiyanju lati gbagbọ pe ayẹwo ti a ṣe si oriṣiriṣi ẹjẹ fi hàn pe eniyan ati ọbọ bá ara wọn tan. Ọjọgbọn kan ti o fara balẹ fiyesi ohun ti awọn ti o ṣe 'ayẹwo oriṣiriṣi ẹjẹ" naa ṣe ti wi pe ki i ṣe ẹjẹ ni wọn ṣe ayẹwo rẹ̀ rára. Iwe Mimọ́ sọ fun ni pe: "Ẹjẹ li ẹmi ara gbogbo" (Lefitiku17:14). Nigba ti awọn ohun ẹlẹmi ti wọ́n wà ninu ẹjẹ naa ba si ti kú nibi ti wọn ti n ṣe àyẹ̀wò rẹ̀, iyè kò si ninu rẹ̀ mọ́; gẹgẹ bi onimọ ijinlẹ tootọ kan si ti wí, ohun ti o kù ti wọn n ri yẹ̀wo kò ju "awọn iyọ̀ kan lasan ti o wà ninu omi - ni pataki iyọ̀ ti a n bù sinu ounjẹ." Nitori naa ayẹwo ti wọn n polongo pe wọn ṣe si "ẹjẹ" kò fi idi ohunkohun mulẹ.

Ọlọrun ti fi iyè ati èémi fun ohun gbogbo, "O si ti fi ẹ̀jẹ kanna da gbogbo orilẹ-ede lati tẹ̀do si oju agbaiye" (Iṣe Awọn Aposteli 17:26). A kò le ti ipa ẹjẹ mọ orilẹ-ède ẹnikẹni – eyi ti o fi idi Ọrọ Ọlọrun mulẹ, pe Ọlọrun ni O fi iyè ati èémi fun ohun gbogbo, "O si ti fi ẹ̀jẹ kanna da gbogbo orilẹ-ede lati tẹ̀do si oju agbaiye."

A le mọ irú ẹranko nipa ẹjẹ rẹ̀. Awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé ti fi Apọsteli Paulu rẹrin ẹlẹya fun "aimọkan" rẹ̀ nitori o kọwe pe: "Gbogbo ẹran-ara ki iṣe ẹran-ara kanna: ṣugbọn ọ̀tọ li ẹran-ara ti enia, ọ̀tọ li ẹran-ara ti ẹranko, ọ̀tọ ni ti ẹja, ọ̀tọ si ni ti ẹiyẹ" (I Kọrinti 15:39). Ṣugbọn lonii wọn ni lati gbà pe otitọ ọrọ imọ ijinlẹ nla ni. Bibeli ati ẹkọ ijinlẹ tootọ maa n bá ara wọn ṣe deedee ni nigba gbogbo. Ọlọrun ni O fi awọn mejeeji fun ni.

**Ofin ti Mendel**

Ọkan ninu awọn ohun àwari ti o ṣe pataki ju lọ nipa imọ ijinlẹ ti o si n daamu awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé ju lọ, ni a pe ni ofin Mendel. Awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye ti n tẹnu mọ ọn pe iru awọn ohun ẹlẹmi "titun" ti jade wá nipa iyipada diẹdiẹ ti o ti n ṣẹlẹ fun ọ̀kẹ́ aimoye ọdun. Ohun ti Bibeli sọ fun ni ni pe eso "ni irugbin ninu"; ofin yii ti Ẹlẹda ti ṣe ni ofin ti Mendel ati awọn ẹlomiran ti ri pe o n ṣẹlẹ ninu gbogbo ohun ẹlẹmi. Ofin Mendel fi hàn pe awọn ohun ẹlẹmi wọnni ti ó fara hàn gẹgẹ bi "titun" jẹ́ àdàlù "awọn ẹ̀ya" atijọ ti wọn ti wà ninu iṣẹda awọn ohun ẹlẹmi naa lati igba laelae nigba ti Ọlọrun ti dá wọn. Ẹni kan ti o gbọ́n ju awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé ti wi pe: "Kò si ohun titun labẹ õrùn."

Ọlọrun ti fi àyè silẹ fun awọn nnkan lati wà ni iru ti wọn ni oriṣiriṣi pupọ. Oriṣi ajá ti o wà to ogoji tabi aadọta, oriṣi ologbo to ogoji tabi ju bẹẹ lọ, irú koriko si to ẹgbẹrun marun-un tabi ju bẹẹ lọ. Anfaani pe ki awọn nnkan le wà ni irú irú ati ni oriṣiriṣi jẹ imọtẹlẹ Ọlọrun ninu ifẹ Rẹ̀ pe ki eniyan le wà ninu itura, alaafia ati igbadun.

Ṣugbọn pe awọn nnkan wà ni oniruuru ko wi pe wọn jẹ ohun ẹlẹmi titun. Ọlọrun ti fi ààlà si i pe olukuluku gbọdọ jẹ "ni irú tirẹ̀." Iwa ti a kò jogun ba ṣugbọn ti a kọ́ kó le ṣe i fi jogun fun ọmọ nipa abinibi; otitọ yii si ti

da ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé rú, nitori o ṣe danindanin pe ki iyipada ti o ba ṣẹlẹ si ohun ẹlẹmi kọọkan hàn ninu ọmọ rẹ pẹlu, ki ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé to le duro. Nibi ti ọjọgbọn kan ti o jẹ olukọ agba ni ile-ẹkọ giga ni Columbia ti n ṣe àyẹ̀wò, o ri awọn "afọju" eṣinṣin kan laaarin awọn eṣinṣin ti o dagba lati inu ẹyin eṣinṣin ti o ti fi sinu igo wara kan ninu imọlẹ oorun. Nitori naa o di dandan fun gbogbo awọn ti n kẹkọọ nipa iwa ajogunba lati tẹwọ gba otitọ yii pe awọn ẹja ti wọn n pè ni "ko loju" kò di a fọju nitori wọn ti wà pẹ́ ninu iho pàlàpálá okuta ti o ṣokunkun, ṣugbọn wọn ti fọju ki wọn to bọ́ sinu ihò, wọn si n gbé ibẹ nitori aabo wà nibẹ. Nitori naa ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye ti o sọ pe awọn ẹja "kò loju" wọnyii ti wọn wà ninu ihò ti o ṣokunkun ti sọ iriran wọn nú nitori agbegbe wọn ṣokunkun ki i ṣe otitọ rara.

Awọn lílì "titun" ti wọn n kokiki pe Burbank ni o ṣe ẹda wọn ni ofin Mendel gbé jade pe wọn jẹ ifarahan titun laaarin awọn lili atijọ, apapọ "awọn ẹ̀yà" atijọ ti o ti maa n wà ninu lili lati igba laelae. Lati fi idi rẹ mulẹ pe wọn jẹ ohun ẹlẹmi titun, awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye gbọ́dọ̀ le fi hàn pe "awọn ẹya" ti o wà ninu ohun titun naa kò si ninu iran rẹ lati atetekọṣe. Eyi ni wọn kò le ṣe. Ofin Mendel duro lonii o si ṣe deedee pẹlu Ọrọ Ọlọrun: "Ni ijọ́ keje Ọlọrun si pari iṣẹ rẹ ti o ti nṣe, o si simi ni ijọ́ keje kuro ninu iṣẹ rẹ gbogbo ti o ti nṣe" (Gẹnẹsisi 2:2). Ọlọrun ni O dá ohun gbogbo ti O si pari iṣẹ Rẹ̀. Ṣugbọn O n ṣe akoso rẹ sibẹ.

**Asọtẹlẹ ati Ẹkọ Ọgbọn Ori nipa Iṣẹdalẹ Aye**

Ohun ti ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye fi gbe ara rẹ lẹsẹ ni egungun awọn ohun ẹlẹmi ti wọn ti kú lati ọpọlọpọ ọkẹ ọdun sẹhin, ti wọn si ti di gbigbẹ bi karawun, eyi ti a n ri ni ira-ira ninu ipele ipele ilẹ, lori awọn oke nla, ati lọna jijin nisalẹ ilẹ, gẹgẹ bi akoko iwalaye wọn ti pẹ to. Gẹgẹ bi igbekalẹ awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye, awọn ohun ẹlẹmi ti o kọkọ́ wà -- bi ẹja kékèké -- ni o wà ni isalẹ ilẹ patapata, "nibi ti ipele erupẹ ti lọjọ lori pupọ pupọ," awọn ohun ẹlẹmi ti o si ti dagba soke pupọ -- bi amọtẹkun, erin ati rakunmi – ni o wà loke ilẹ patapata "nibi ti erupẹ ṣẹṣẹ ga dé." Ahesọ ọrọ lasan ti awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye gbé kalẹ ni eyi jẹ́ lati fi gbé ẹkọ wọn ró. Wọn ko i ti walẹ de ipilẹ ayé lati yẹ karawun ti n bẹ nibẹ wò. Ibi ti eniyan si ti i walẹ jin de ni mile mẹwaa si isalẹ, nibi ti wọn ti n wá epo mọto kiri. Awọn ti o ni oye gidi nipa ohun àlumọ́ni inu ilẹ n jẹwọ pe ko si ọna ti o daju lati fi mọ bi awọn apata ti darugbo tó. A kò ba wọn ni ira ira gẹgẹ bi ọjọ ori wọn. Lodi si eyi, ni ibi pupọ ni o jẹ pe bi awọn ajẹbo ilẹ ti wà lori ara wọn ṣe atako bi awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye ti sọ pe o gbọdọ jẹ́. Ni ilu China, Norway, Alps, Scotland, New York, Tennessee, Georgia, Idaho, Montana, Alberta, ati ni ibi pupọ miiran, awọn ohun ti wọn wi pe o gbọdọ jẹ "karawun ti o darugbo" ni a n bá pade ninu "ipele erupẹ titun" ati eyi ti wọn wi pe o jẹ "karawun titun" ni o wà ninu "ipele erupẹ ti o ti darugbo." Ọjọgbọn pataki kan ninu ẹkọ ohun alumọni inu ilẹ ti sọ otitọ inu rẹ pé: "Mo ni oye to ẹnikẹni nipa bi wọn ti n ṣiro ọjọ ori ohun alumọni inu ilẹ, mo si le fi gbogbo ẹnu sọ pe akọsilẹ ti a wi nipa ilẹ kò fi àyè gbolohun ọrọ kan silẹ ti o le fi idi arofọ Darwin mulẹ."

**Ìkún Omi**

Nigba ti awọn ọjọgbọn nipa ohun alumọni inu ilẹ ti o gba ẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ aye gbọ́ ba ri ohun ti o tako ẹkọ wọn, wọn a pe e ni "àbùkù," a si wa di ọranyan fun wọn lati wi pe o ni lati jẹ pe agbara nla kan ni o rú awọn oke soke ti o si ti wọn fun ọpọlọpọ mile dé ipò "abuku" ti wọ́n ti ba wọn. Ọjọgbọn miiran nipa ohun alumọni inu ilẹ jẹwọ pe "ohun ti o hàn kedere jẹri lodi si arofọ pe iru nnkan bẹẹ ti ṣẹlẹ ri.' Ṣugbọn Iṣẹlẹ Ikun Omi nla ni mu un yé ni bi awọn apata ṣe wà bẹẹ. Kò ṣoro lati ri i pe ọ̀gbàrá omi ti Ọlọrun rán ni akòkò Ikun-omi, ati awọn igbi omi nlanla ti o bo awọn oke mọlẹ, yí oju ilẹ pada patapata ni akoko Ikun-omi naa, ati lai ṣe aniani, fun igba pipẹ́ lẹyin naa. Alagbalugbu ọ̀gbàrá omi ti o dà silẹ lati ori awọn oke giga, ti o si wọ́ lọ sinu awọn okun le gbẹ́ afonifoji, ki o bi apata lulẹ, ki o si di ọna omi nla ati odo ṣiṣan: "Omi si gbilẹ gidigidi lori ilẹ" (Gẹnẹsisi 7:19).

**Ibi Ti Karawun Gbé Wà Ninu Ilẹ̀**

Arofọ yii pe isalẹ awọn okun "rú soke," awọn iyangbẹ ilẹ si wọlẹ̀ leralera fun ọpọlọpọ aimoye ọdun, jẹ ọrọ ti awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé n polongo ṣugbọn ti wọn kò le fi idi rẹ mulẹ. O rọrun diẹ fun wọn lati tẹnu mọ arosọ yii nigba ti awọn eniyan ro pe inu ilẹ lọhun wà ni yiyọ́ bi epo gbigbá. Ṣugbọn lọjọ oni, awọn ọjọgbọn gbagbọ pe ohun ti o le koko bi irin ni o wà nibẹ, eyi si jadi ahesọ pataki miiran ninu arofọ awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé. Ohun ti o mu ọgbọn wá ni lati gbagbọ pe Ikun Omi nla nì ni o fa a ti karawun awọn ohun ẹlẹmi igbà nì fi wà ni ibi ti a ti n ri wọn.

**Wiwà Bakan Naa Titi Lọ**

Ọrọ awọn ẹlẹkọ ọgbọn ori nipa iṣẹdalẹ ayé pe lati inu awọn ohun ẹlẹmi ti ko ni laari bi dègbènseri ni awọn ohun ẹlẹmi bi erin, ọbọ ati eniyan ti dagba soke nipa iyipada ti o n ṣẹlẹ diẹdiẹ fun ọkẹ aimoye ọdun sẹyin, ati pe

bakan naa ni iyipada diędię yii yoo maa tę siwaju titi lae, to bęę ti ohun ęlęmi titun yoo fi maa wáye nigba gbogbo ję ęri si ọrọ Iwe Mimọ́ pe awọn kan yoo maa sę́ ipadabọ Oluwa, wọn o si maa wi pe, "Nibo ni ileri wíwa rę̀ gbé wà? lati igbati awọn baba ti sùn, ohun gbogbo nlọ bi wọn ti wà rí lati ìgba ọjọ ìwa." Peteru Apọsteli fi sísę́ ti awọn ęlękọ ọgbọ ori nipa ișędalę aye n sę́ bibọ Oluwa kọ́ akọsilę Bibeli nipa Ikun Omi nigba ti o wi pe; "Nitori eyi ni nwọn mọ̃mọ ṣe aifẽmọ, pe nipa ọ̀rọ Ọlọrun li awọn ọrun ti wà lati ìgba atijọ, ati ti ilę yọri jade ninu omi, ti o si duro ninu omi; nipa eyi ti omi bo aiye ti o wà nigbana, ti o si ṣegbe" (II Peteru 3:5, 6).

**Ohun Ti Igba Yoo Fi Hàn**

Aimoye ọgọrun-un arọsọ èké ti o ti wà ni awọn ti o ni oye nipa imọ tootọ ti já ni iró̩ ti wọn si n já titi di oni-oloni. Bibeli ti bori atakò awọn ọba, awọn wolii eke, awọn eke ọjọgbọn, ati awọn ti o wi pe Ọlọrun kò si. Lonii a n gbọ́ pe ękọ ọgbọn ori nipa ișędalę aye ti "kùtà," awọn ọjọgbọn ninu imọ ijinlę tootọ ti kọ ọ silę. Bi imọ ti o ṣe e gbękę le ti n tę̀ siwaju ni a n ri i pe imọ ododo ati tootọ ni gbolohun kọọkan ti o wà ninu Bibeli. Ęmi Mimọ ni o mí si awọn ti o kọ Bibeli ati imọ ijinlę wọn, Ęmi Mimọ si wà nibę nigba ti a ṣe ęda ohun gbogbo: "Ęmi Ọlọrun si nràbaba loju omi."

Itan Bibeli nipa didá ayé sọ fun ni bi eniyan ṣe wáyé. "Bẽli Ọlọrun dá enia li aworan rę̀" (Gęnęsisi 1:27). Ohun ti ęlękọ ọgbọn ori nipa ișędalę aye le sọ nipa ipilęșę eniyan ko ju pe "o ṣe e ṣe ki o ję bayii," tabi ki o jęwọ pe oun kò mọ̀. Gęgę bi arosọ awọn ęlękọ ọgbọn ori nipa ișędalę aye o gba ọkę aimoye ọdun ki aye to yọri si bi o ti wà bayi. Ọjọ męfa pere ni o gba Ọlọrun lati dá ohun gbogbo nipa ọ̀rọ Rę̀, wakati męrinlelogun ni o si wà ninu ọjọ kọọkan wọnyii. "Nipa ọ̀rọ OLUWA li a da awọn ọrun; ati gbogbo ogun wọn nipa ẽmi ęnu rę̀" (Orin Dafidi 33:6).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti awọn ti o wi pe Ọlọrun kò si ati awọn ęlęgan fi ni itara lati mọ̀ nipa bi eniyan ṣe de aye jù lati mọ̀ bi aye ti dagba to lọ?
2. Ki ni ṣe ti arosọ pe ohun ęlęmi kàn dédé wà bęę funra rę ni, kò mú ọgbọ́n wá?
3. Ki ni ohun ti ṣęlę nipa eyi ti a le fi ṣe alaye ipo ti awọn apata wà?
4. Ki ni ikuna pataki ti o wà ninu pe a n yę ęję wò?
5. Ki ni ohun ti Paulu Apọsteli sọ ti a si ti ri pe otitọ imọ ijinlę nla ni?